# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 607 MONDAY MAY 18, 1964 (2D)


## Ọkunrin Kan Yin Ararẹ Ni'bọn !

IBADAN:- Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati nwọn gbọ iro ibọn ni ojiji ti nwọn si sare wọle ti nwọn ba Ọkunrin kan, David Daniel Fadare, ẹni Ọdun mejidilọgọta ninu iyara rẹ ti npọka iku ninu agbara ẹjẹ ti nwọn si ba ibọn Olojumeji kan ni ẹgbẹ rẹ ni ọjọ Ẹti ti iṣe Ọjọ kedogu Oṣu yi ninu ile rẹ ni Idi-Oro.

Ọkan ninu awọn iyawo meji ti ọkunrin na ni ṣe alaye fun Oniwe irohin wa pẹlu omi oju pe, Ọkọ awọn ṣẹṣẹ gba isimi ifẹhinti lẹnu iṣẹ ni, Eko ni o ti nṣiṣẹ, nigbati o si gba isimi ifẹhinti ni gbogbo awọn ba ṣe wa si Ibadan ti awọn si pinnu lati ma a gbe ile awọn ni Idi-Oro ni nkan bi Oṣu mẹta sẹhin.

O tun ṣe alaye siwaju pe Ọkọ awọn ko ba awọn sọ nigbakan ri pe on wa ninu Okeiṣoro kan, a fi igbati awọn gburo ni Ojiji ati lairotẹlẹ ti o yin ara rẹ nibọn,

Lẹṣẹkẹṣẹ ni awọn ara ile na sare lọ si Tesan awọn Ọlọpa lati lọ fi Ọran na han awọn Ọlọpa ni Tesan. Ko pẹ pupọ lẹhin na ti awọn Ọlọpa fi de, nwọn ṣe ayewo Ọkunrin na, nwọn si ri pe, on lo yinbọn Olojumeji rẹ pa ararẹ.

Awọn Ọlọpa ti gbe oku Ọkunrin na lọ si ile iwosan lakulaku, nwọn si nṣe iwadi lọwọ, ohunti o le mu ki Ọkunrin na o yin ararẹ nibọn,

## "Ẹṣẹ Awọn Olujẹjọ Ko Fẹsẹ—Mulẹ, O Si Fẹ Ijinlẹ Irona"

# ẸJỌ OLOYE AWOLỌWỌ PARI, O KU IDAJỌ

Idunnu subu lu ayọ, ayọ si subu lu oyin nigbati irohin de etigbọ gbogbo enia ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi pe, adajọ Agba, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla, olori gbogbo awọn Adajọ fun Apapọ Ijọba Naijiria ti da awọn enia mẹrin silẹ ni ayọ ati alafia, ninu awọn enia metadinlogun ti Ijọba mba ṣe ẹjọ iditẹ ati lati fi ipa ko nkan ija ogun wọlu lọna ti o lodi si ofin.



Ọgbẹni Durand
Agbẹjọro Awolọwọ

Ọrẹ di boo lọ oya fun mi nigbati awọn enia na kọkọ gbọ irohin na ninu ẹrọ asọromagbesi ti hal si ṣe gbogbo enia pe, "Irọ ni tabi ootọ ni" nigbati nwọn kọkọ gbọ.

Gbogbo enia lo nsare lọ si idi apoti ẹrọ asọromagbesi nigbati nwọn gbọ pe adajọ ti fi awọn enia mẹrin silẹ nwọn si fẹ lati mọ oruko awọn enia mẹrin na

Orukọ awọn enia mẹrin na ni wọnyi :- Oloye Samuel Ọrẹdẹin, Ọga Agba akọwe eto idasilẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre, ẹniti adajọ Ṣowẹmimọ ṣe idajọ ẹwọn ọdun meji fun.

Ọgbẹni Joseph S. Ọlawọyin, Akọwe agba ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ipinlẹ Ariwa, ti o si tun jẹ ọkan ninu ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Ariwa ẹniti adajọ Ṣowẹmimọ ṣe idajọ ẹwọn ọdun mẹta fun.

Joseph O. Lawanson igbakeji akọwe agba eto idasilẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre ẹniti adajọ Ṣowẹmimọ ṣe idajọ ẹwọn ọdun meji fun ninu ọdun to kọja.

Joshua Akamọ ọkan ninu awọn amugbalẹgbẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre, ẹniti adajọ Ṣowẹmimọ ṣe idajọ ẹwọn ọdun mẹrin fun.



Ọgbẹni Kellock
Agbẹjọro Awolọwọ



Oloye Awolọwọ

Idasilẹ awọn enia mẹrẹrin wọnyi ba gbogbo enia ni ojiji ati lairotẹlẹ ti o fi ya gbogbo enia lẹnu nitoripe, awọn enia lero pe nigba kanna ni adajọ yio ṣe idajọ wọn.

Ọlọla Adetokunbọ Ademọla sọ ninu ile ẹjọ na pe, lẹhin igbati awọn ti gbọ ẹjọ na lati ibẹrẹ titi de opin, awọn ri daju gbangbape, kosi ẹsun kan ti awọn ri ka si awọn enia mẹrin na lẹṣẹ, ko si ni dara lati tun da wọn duro si ọgba ẹwọn,

Adajọ agba na tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe" ki iṣe wipe mo sọ pe awọn enia yoku jẹbi, ṣugbọn o fẹ ronu gidigidi si ẹjọ wọn, ki asi mọ ọna ti adajọ ti o ṣe ẹjọ na tẹlẹ gba,,


Wo Oju Ewe Kẹfa




Ọlọla Ade. Ademọla
Olori awọn Adajọ





The NEW de luxe HOOVER cleaner

Buy yours NOW at :

LEVENTIS TECHNICAL

New showrooms at Iddo, Marina & Mainland Stores, Kingsway, P.Z., U.T.C. Stores and also throughout our branches in Nigeria.

# YẸYẸNATU

## Oni Yẹyẹ Eko

Yẹyẹnatu:- Nko mọ pe mo ṣe pataki ni ilẹ yi.

Olotu:- Ha, oni yẹyẹ Eko ni ọ kẹ

Yẹyẹnatu:- Yẹs. ṣugbọn iyẹn ni ko jẹ ki nwọn ka ọrọ mi si tẹlẹ

Olotu:- Nisisiyi nko?

Yẹyẹnatu:- Ha ti sisi Akin rera ni on fẹ pe mi ni aleio

Olotu-; Nitori kini?

Yẹyẹnatu: O ni mo fi on ṣe yẹyẹ, mo ni ṣe gbogbo ohun ti nba sọ sa ni yẹyẹ? Mo ni ṣe mo purọ ni pe awọn gba leti ribi oku ijeelo?

Olotu:- O tun bere bẹ

Yẹyẹnatu:- Haha, ewo lo kan mi, lo ba binu, o ni on yio fi bi on ṣe jẹ han mi

Olotu:- Iwọ ko mọ bi o ṣe jẹ tẹlẹ ni?

Yẹyẹnatu:- Nko fe moolu rẹ ni, tani ko mọ Akinrera? Tani ko mọ pe o ja ọkọ silẹ nitori ati ṣe wundia ni, tani ko mọ ilumọmika, sisi ilu

Olotu: Ṣe o sọ gbogbo eyi na fun?

Yẹyẹnatu: Nko wi fun Ha bi nba sọ eyi, boya ki ba ti fori sọlẹ

Olotu:-Nwọn sọ fun ọ pe o ni iti loju ni?

Yẹyẹnatu: Iti loju kẹ, dipo iti loju, eyi to ku ninu irun oju rẹ ọbẹ lo fi rẹ lo nkun oju bi abo gẹlẹdẹ.

Olotu:- Ṣe o dara to gẹlẹdẹ ṣe?

Yẹyẹnatu:- Dara to gẹlẹdẹ kẹ? Ni ẹniti mo sanra julọ.

Olotu; Ṣọra rẹ ṣa nitori ko ma fiya jẹ ọ.

Yẹyẹnatu:- Fiya jẹ tani? o to bẹ

Olotu;- Iwọ lo mọ pe a ju ara wa nilẹ yi ṣa

Yẹyẹnatu- Nl pe ki ẹnikan fiya jẹ mi lesan nilu ti Ijọba wa

Olotu: Ha ha ha mo sorry fun ọ Bi o ko gbogbo gbọ rẹ, o ko gbọ ti Ileṣa ati Akurẹ? Tabi o ko si ni ilu nigbati Ijọbapaṣẹ pe ki adajọ yọ ọwọ kuro lọrọ awọn ti o nwa ika ni Akurẹ

Yẹyẹnatu:- Iyẹn yato, ṣe awọn ni nitoripe iranṣẹ N N D P ni wọn ni.

Olotu:- Hẹn, iwọ mọ awọn ti sisi Akinrera ma si ọ ni,

Yẹyẹnatu:- Ẹro pe o le ran things NNDP si m ni nigbati on ki i se NNDP

Olotu:- Iwọ mọ eyiti nse? O bi i

Yẹyẹnatu:- Hẹn ko ran awọn ẹni ana ṣe fun pe o Lere

Olotu:- Owo ti mo le ya ọ sa ni pe ki o ṣọra rẹ Nko ba ẹnyin mejeji wi Eyiti nṣe yin ni yẹn.

Yẹyẹnatu: Ewo lo nṣe ẹnyin

Olotu;- A ni ki ijọba fi kun owo osiṣẹ were

Yẹyẹnatu:- Iyẹn lo ṣe ẹnyin Ti oṣiṣẹ kọ ni o nṣe awa. eyiti nṣe wa le ju iyẹn ṣugbọn o jọra

Olotu:- Ewo ni yẹn?

Yẹyẹnatu;- Awa Obirin nṣe ipabe nisisiyi pe o yẹ ki awọn Okunrin fi kun owo ọbẹ.

Olotu:- Haha, ijọba ko yi fi kun owo iṣẹ kẹ

Yẹyẹnatu:- Yes, ṣugbọn alata ati oniyọ ti elẹran paapaa ti fi kun owo oja

Olotu:- Ha iṣekuṣe ni yẹn

Yẹyẹntu:- Ẹ ọ tan, ejọ awa obinrin kọ

Olotu:- Hẹn Ọkunrin wo lo ma a da yin lohun

Yẹyẹnatu:- Ti nwọn ko ba dahun awa na ti pinnu lati da iṣẹ silẹ.

Olotu:- Hahaha, ẹ da iṣẹ silẹ

Yẹyẹnatu:- Yẹs kọ, ohun to kan se mi lanu ni pe awọn oniṣẹ larin wa ti awọn ni ẹgbẹ ti awọn lọtọ awọn si t fi owo le ori orun kọkan nitorina ohun ti a ba se ko kan awọn

Olotu:- Yẹs, ko kan wọn kẹ seti nwọn ko ni ọkọ

Yẹyẹnatu:- Ha burọda ti a ba da iṣẹ silẹ awọn to ma a moolu ọkọ tiwa niyẹn-

Oloto:- Ẹru iyẹn nba ẹny ni

Yẹyẹnatu:- Ki nsotitọ emi ko jẹ ba ẹnikan da iṣẹ silẹ Laiye ti Obirin ti nwa ọkọ bi ọkọ mi pọ ni ilu Ọkunrin wo lo le gba ki nma sọrọ Hausa ki nma ṣe lyawo on.

Olotu:- Ko pọ looto.

Yẹyẹnatu:- Ṣugbọn on na njaiyẹ rẹ ṣ o.

Olotu: Yẹs ṣa moju kuro ni ẹni ba fẹ gbajuinọ fẹ iyọnu.

Yẹyẹnatu:- Ẹnyin mọ yẹn ohun ti mo like yin fun niyẹn burọda, ẹ ma gbadun o jare.

## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ

## Apejuwe Ile isẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sọkalẹ ni Lawanson, bere ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igbo Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Orumi Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin titẹ ati Etutu Ṣiṣe | |
| Iwe Afọṣẹ Isẹdale Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Iṣẹgun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6 |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/6 |

J.O. Shoyinkan
c/o Postal Agen
Itirẹ Via Suru Lere,
Yaba.

or 1, Ishiba Street (Odo Ẹran)
ITIRẸ


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin g bog



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa la ọkun lọsin tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara awọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn a lera gbogbo nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun ọ si ded'adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, ojo rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos.

# Isinku Wolemotu Dun

EKO:- Ese ko gbeji ni ibi isinku iya oninure ti oruko re nje Wulemotu Disu aya ologbe Oseni Kehinde D.su ti o jailaisi ni oru ojo eti ti ise ojo kini osu yi Nwon si gbe oku re, lati ile ni Idolu lo sin ni ojo keji ti o lo je ipe Olorun nigbati o di eni odun merindinlogorin' Ni ite oku Okesuna ni nwon si sin in si.

Awon omo oku na ni awon Iyaafin Abusatu Ajiwun Bello SimbiatuApinke Kofi, Anotu Ayoka Kareem Ogbeni Tauridi Disu ati Omidan Monsunatu Abeke D su ati awon ebi Disu lokunrin, lobnirin na wabi wosi owo ni ibi aseye isinku na.

Ogbeni Mumuni labi Disu. A haji Y. A Disu awon Iyaafin Ejide Iya Oyo Disu Rabiatu Gbajabiamila, Muninatu Giwa ati Tayiba u Disu se tebe ni bi i aseye isiku na.

Omoluwabi ti o ni lakaye sinu ati iwa irele ti o si korira isokesodo a'i iwa kenimani ni ologbe na ni igba aiye re. Ki Olorun ke e o ki o ge e.

## Barika Re Hadji Disu

EKO:- Opolop awon Ahladji ni nwon ba oko ofurufu de si Naijiri lenu lolovi lati Ile Mim -Meka ati Medina awon bi Hadji Abudu Ganiyu Adebayo Disu. Hadji- Imam Muhamed Bus ri Kogberegbe ati Hadja Kudiratu Ajile Disu. Nwon si gbayigbeye.

Nwon nawo nara, nwon si lo se isin akan se (idupe) ni Mesalasi Jimo. Ki Olorun tubo se apole won o,ki nwon si n emi gigun ti oni O ore ninu.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan. 22-Feb. 20) Are yio mu o die, gbogbo re yio su o go o. Mase b a awon ebi re se aawo loni, beni ki o jina si awawi.

PISCES (Feb. 21-March 20) Mase nkan pakanleke, nkan yioolo fun o lale oni. Gbogbo awon ti o nfe, ko mo ohun t i iwo nf e pataki awon obinrin. Bope titi ohun ti o nfe yio ye won.

ARIES (March 21-April20) Mase jeki inu re baje loni ohunkohun nitoripe bi ekun p e di ale ojo kan, ayo mbo ni owuro kutukutu. Je ki inu re ma dun si ise ti o nse.

TAURS (April21-May 20) igba ayo yio yide fun o, mase fi ise re sere, mu dan girigiri, odaji pe iwo yio niyawo kan, e mase tete fun ara nyin ni oruka, ki boko arede nyin ko ni pe tuka.

GEMINI (May 21-June21 :- Boya, o le ti rse asise kan, gbidanwo lati tun ona na se, toju ise e ki o si ma moju to, lo dubule, ki o sun kakangki o si ronu wo Ki ogbon le wo inu re

CANCER (June 22-July 23 : Ki o to le ma se ayonusi oro, ko lati ma ko ara re nijanu Mase fe lati maje ajeki onje ki o ma ba se o ni aisan.

LEO (July 24 Aug 22 Ohun kan ti o ti nfe lati ni, ti ko si aye re fun o, yio bosi fun o lati ni. Mase ko egbe buburu ki o ma ba so o ni oruko o si le ba o ni oruko je, tobe ti o le di ero ehin.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Jeki okan re soji ni ale oni, iwo yio ba enikan pataki kan pade ti oro re yio jo eyiti o nfe ipade re pelu obirin kan yio larinrin Inu awon ebi re yio dun si ipapo iwo pelu awon egbe kan

LIBRA (Sept. 21-Oct 23) Lowuro ojo oni iwo yio je anfani ore, sibe mase fi ara sile fun. Iwo yio ri ere je lori irinajo kan ise yio gbe e lo si dale ewu mbe fun o

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Iwa re lo sunwon, awon o faye gba o lati soro kan ni itunbi inubi, Bi o ba si je nit o nta te e, asiko re niyi, owo girimoyan ni iwo yio ri gba nidi tete na bi o ba ta.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec. 22) O ti sise pupo ju, alafia yio to o, ero oka re dara, arisiki re si si goboyi. awon oku orun nse adura fun o.

CAPRICORN (Dec 23-Jan 21) Ohun kan ti o nbo ni asiri yio je ire fun o loni, o si le ri alatako nipe, iwo pelu awon ebi re ko se rere to,


BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI NWON NPE NI - Eleyi yato patapata si awon

**RICHALET**

Robi-robi. Ise re lara enia ju da si fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu EJE ARA' bi Monamona,

FUN ARUN EJE ARA ENIA GBOGBO




Meji re ko si ni gbogbo awon Egogi ti nwon npe ni TONIKI Eje ti nwon si ni kakiri ni owo pooku adimowo tabi ki o lo nile ko di o wo Iyen se ewo, awa ki ta awon egbogi ba won yen rara tabi ti nwon npo ta ni le yi,

Gegebi awon Onibara wa ti mo irufe awon egbogi ba won yen a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranse fun tita lati awon ilu Jamani, Faranse ati ti awon Latembulu si Itali je

Mo daju pe, bi eje ara ko ba mo daradara awon amodi tabi ailera wonyi le se o, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju susu tabi didun. Jedijedi Akoba, arun Edoki, Aya didun pupo ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilo, ehin didun tabi baradi riro pelu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba eje ara re patapata yio si ni eje re mo tonitoni pelu.

Sa dan igo re kan wo iwo yio si ma a rohin re fun elomiran pelu.

Bere Sobu awon:—

Waterloo Medicine Store
3, Palm Church Street ( Lagos.
Phone 22878 Nigeria, Oja Ita Faji)



BI O BA NI

**Iwe—Tite**

FUN

**Lilo nibi Ise re tabi orisirisi iwe itufo tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe gbeyawo**

TETE KOWESI ILE—ISE—ERO ITEWE

**Modupe Printing Press**

16 Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ERO ITEWE WA NHAN

*OWO POKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lekansoso ki o ri iyato*

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 607 MONDAY, MAY 18, 1964 (2 [illegible])


## Ọga Ọlọpa Kan Pade Iku Ojiji!

SHAGAMU:— Gbogbo enia bẹrẹsi gbọn titi bi igbati alupupu ti o bajẹ ba fẹ gun ori oke nigbati ọkunrin kan, Ashimi Ayọ Disu, ẹni ọdun marundi logoji ti o nwa mọto awọn Oyinbo elepo mọto nwa mọto rẹ lọ ni oju ọna ti o si kọlu mọto Ọgbẹni Aba Okon, ọkan ninu Ọga awọn Ọlọpa Ibadan ti Ọga Ọlọpa na si ( bamubamu ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kesan oṣu yi.

Ẹniti ọrọ na ṣoju rẹ ṣe alaye fun oni we irohin wa ni Shagamu pe, mọto Ọga Ọlọpa na nlọ niwaju, o npada lọ si Ibadan lẹhinti o ti pari iṣẹ rẹ ti o wa ṣe ni Shagamu tan, Nigbati Ọgbẹni Disu ri mọto Ọga Ọlọpa na niwaju ni o ba gbiyanju lati sare bọsi iwaju mọto Ọga Ọlọpa na, ṣugbọn kọna kan wa ni ọkankan ibẹ ni o ba kọlu mọto Ọga Ọlọpa na.

O ni nigbati gbogbo enia ti o wa ni tosi gbọ ariwo, ni nwọn ba sare de ibi ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ, ti nwọn si ba mọto Ọga Ọlọpa na ti o ti bajẹ bi nwọn ti yẹju wo inu mọto na ni nwọn ba ri Ọga Ọlọpa na, nwọn si sare gbe lọ si Ile-iwosan ṣugbọn Ọga Ọlọpa na tiku.

Awọn Ọlọpa ti mu Ọdaran na lọ si Ile ẹjọ fun ẹsun pe, o wa mọto rẹ ni iwakuwa pẹlu iafara lọna ti o lewu o si pania. Adajọ ti yẹ gbigbo ẹjọ na si ọjọ iwaju, bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si ẹ o maa gbọ o.

LATI OJU EWE KINI

Ṣugbọn o pari ọrọ rẹ pe, "lati ibẹrẹ de opin, on kori ẹjọ kan, tabi ẹṣẹ kan ti enia le ri gbamu pe awọn enia na ṣe, Ṣugbọn ọrọ wọn fẹ ijinlẹ ironu gidigidi"

O wa pari ọrọ rẹ pe, "A ti gbọ gbogbo ohun ti ẹ wi patapata, ẹ ku iṣẹ, agbẹjọro Ijọba ati ti awọn olujẹjọ, gbogbo nyin ni a ki, ẹjọ yi le pupọ, ṣugbọn a dupẹ fun gbogbo bi ẹjọ na ti lọ ati irinsi awọn enia na pẹlu aṣiṣe adajọ ti o ṣe ẹjọ na tẹlẹ eyiti ẹ ti pe akiyesi wa si, ẹ ku iṣẹ o"

Lẹhinna ni o wa kọju si ọgbẹni Victor Durand, ọjọgbọn Oloye Amofin, Oludamọran Ọbabinrin Gẹẹsi ati Ọgbẹni Thomas Kellock awọn Oyinbo mejeji ti nwọn ṣe ẹjọ awọn enia na.

O wa pari ọrọ rẹ pe, "A lero pe, nigbayowu ti ẹ o ba tun pada wa si Naijiria ki iṣe nipa iru ẹjọ bayi, ni ẹ o ba wa, a dupẹ lọwọ nyin pupọ, a dele ba ire o"

Ṣugbọn eyi ni Ọgbẹni Thomas Kellock ti sọrọ niwaju Igbimọ ijoko awọn adajọ marun ti nwọn ngbọ ẹjọ na on ni o si sọrọ gbẹhin ninu gbogbo awọn Amofin.

O ṣe alaye pe, awọn enia na ko jẹbi, adajọ ti o ṣe ẹjọ na tẹlẹ lo ṣi ara rẹ lọna, o si rọ ile ẹjọ lati tu idajọ adajọ Ṣowẹmimọ ka, ki nwọn si fi awọn enia na silẹ layọ ati ni alafia.

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, nigbati awọn ẹlẹri na ti nwọn njẹri fun ile ẹjọ de Ghana ti nwọn mọ pe iṣẹ ti awọn lọ kọ ni Ghana ko dara, kini ṣe ti nwọn ko sọ, ti nwọn fi wa nsọ niwaju adajọ?

Ademọla: Ṣe o mọ pe ajeji ni nwọn jẹ ninu ilu na."

Kellock; "Iyẹn ni pe ko si awọn ọmọ Naijiria ti nwọn ngbe Ghana ti nwọn le sọ fun Mo lero pe ọmọ Naijiria pọ ni Ghana."

Ademọla:- Awọn ọmọ Ipinlẹ Ariwa ni agbegbe Tiv ni awọn enia na."

Kellock; "O yẹ ki nwọn le ri enia kan ti nwọn le ba sọrọ na, ki nwọn to maa wa sọ ni ile ẹjọ pe, nigbati awọn de Ghana ni awọn to mọ iru iṣẹ ti awọn lọ kọ, ṣugbọn, ẹnyin mọ awọn enia Naijiria ju bi ẹ ti ṣe mọ wọn lọ."

Lẹhinna ni o wa mu ẹnu kan ẹjọ ti ọgbẹni Patrick Dokotiri, ti o sọ pe, Tarka sọ fun on pe, on (Tarka) le ri awọn ọmọkunrin ti yio lọ si Ghana lati lọ kọ iṣẹ ogun.

Taylor: "Ṣugbọn o sọ pe ki a ko awọn ẹlẹri Ijọba?'

Kellock: "Nigbati ọrọ awọn ẹlẹri ko ba dọgba, gẹgẹbi bi iṣẹ mi, o yẹ ki nle pe akiyesi nyin si i."

Ademọla:' O sọ lẹkan pe, awọn kan fẹ lọ sapamọ ni ori oke kan ki nwọn si ma ṣe ohun ijamba ninu ikọkọ, mo lero pe oloye Awolọwọ ni wọn sọ pe o fẹ ṣe bẹ ni?"

Kellock: "Mo kan sọ eleyi ni nitoripe, Adebiyi sọ pe on gba idajọ adajọ na gbọ pe, o dara.

Ademọla: "Mo nwoye rẹ pe ẹlẹri Ijọba wo lo sọ ọrọ na niwaju Ṣowẹmimọ?"

Kellock: "Alhaji Ibrahim Imam nikan lo sọ bẹ."

Ademọla: Mo gbọ ti o sọ pe Dokọtri lo sọ bẹ lẹkan, mo si fẹ pe akiyesi rẹ sii pe, ki iṣe bẹ rara."

Kellock: Gbogbo akiyesi ti ẹnyin nṣe, adajọ ti o ṣe ẹjọ na tẹlẹ ko bikita fun."


## AFRICAN SPECIAL

- Full tropicalisation and underbody protection plates
- Strong and comfortable suspension.
- Outstanding road holding.
- Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
- HIGH RESALE VALUE.




## LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.



Printed [illegible] 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor;- TUNJI AJ[illegible] 45, Campbell Street, Lagos 18[illegible]